# Ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ Ìdási Ìhùwàsí fún Tîìkì (CBIT)

Àjọ Tourette Tí Ìlú Amerikà
Ìtanilólobó. Ìwádìí. Àtìlẹ́yìn.



42-40 Bell Blvd., Suite 205, Bayside, NY 11361 **tourette.org 888-4TOURET**

2__TAA-CBITEnglishRevisedFINALsepPages_YO.indd 1 6/9/2022 12:41:26 p. m.



Ní ọdún 2001, Àjọ Tourette ti Ẹ́gbẹ Ìmọ̀-ìjìnlẹ̀ nipa Ihuwasi ti ilẹ Amẹrika ṣe àyẹwo ati àtẹ̀jáde iṣẹ ìwádìí nla àkọ́kọ́, àtẹ̀jáde yii fi hàn pé ìtọ́jú láìlooògùn le mú àdínkù ba tîkì tí ó le. Itọ́jú yii ni à ńpè ní Ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ Ìdási Ìhùwàsí fún Tîkì (CBIT) (wo-bit). Àgbékalẹ̀ ètò ìtọ́jú àìlera tuntun mú ireti nla ati idunnu wá sí agbègbè Tourette Syndrome (TS). Èrèdí ìwé pélébé yii ni lati fi CBIT hàn ọ́, lati jẹ ki o mọ awọn ìbéèrè tí ó wọ́pọ̀ nipa itọju naa, lati jíròrò lori ìmúnádóko ìtọ́jú CBIT, ati lati ṣapejuwe bí o ṣe le rí akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ olupese CBIT.

## Kíni CBIT?

CBIT jẹ itọju aláìloòògùn fun tîkì, eyiti ó ní awọn abala pataki mẹta:

(a) Kíkọ alaisan ní ẹ̀kọ́ lati mọ̀ síi nípa àkùdé ara Tîkì ti ó ni ati ìmọ̀lára pé ìṣesí tîkì fẹ́ ṣe wọn.

(b) Kìkọ̀ aláìsàn lati hùwà mìíràn tí ó yàtọ̀ nígbà tí wọ́n bá ní imọ̀lára pé ìṣesí tîkì fẹ́ ṣe wọn.

(c) Ṣíṣe àyípadà sí àwọn iṣẹ́ ojoojúmọ́ ní ọ̀nà tí ó lè ṣe ìrànwọ́ lati dín àrùn tîkì kù.

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ awọn ilana yii ni a ti ń lò ní ọ̀pọ̀ ìgbà fún ìṣàkóso àwọn ààmì aisan TS. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ awọn agbalagba tí wọ́n ní TS jábọ̀ pé wọ́n se àwárí awọn ọ̀nà ìṣàkóso tîkì tó farapẹ́ ti CBIT. CBIT ń lo àpapọ̀ àwọn ọgbọ́n àtínúwá tó múnádókò pẹlu àwọn ìlana tí ń ran àwọn eniyan lọ́wọ́ lati tètè kọ́ nipa àwọn ìlànà naa.

## Bawo ni o ṣe lè kọ́ ẹ̀kọ́ nìa CBIT?

CBIT jẹ́ ọ̀nà itọju ailera tí ó ní ètò tí ó ga jùlọ́ èyítí onișegun ń ṣàkóso rẹ ní ẹẹkan lọ́sẹ̀. Ìpàdé pẹlu onisegun ní mẹjọ láàrín ọ̀sẹ̀ mẹwa ní ọ̀nà ìtọ́jú tó pegedé, ṣugbọn a le ṣe àtúnṣe rẹ lati ba àìní alaisan ati awọn mọ̀lẹ́bí rẹ pàdé. Ìgbésẹ̀ àkọ́kọ́ fún CBIT ni lati kọ alaisan lati mọ̀ nìpa tîkì ati àwọn ìmọ̀lára tí wọ́n maa ń ní kí ìṣesí tîkì tó ṣe wọn. Ìgbésẹ̀ tí ó tẹle ni lati kọ alaisan ní ìwà tàbí èsì tó figagbága pẹlu ìṣesí tîkì èyí tí alaisan lè lò nigbati ó bá kẹ́ẹ́fín ìmọ̀lára ìṣesí tîkì tàbí tí wọ́n bà kẹ́ẹ́fín pé tîkì ń ṣe wọn. Ìwà tó figagbága pẹlu ìṣesí tîkì jẹ ìwà tàbí ìṣeṣí tí yoo mú ki ó nira fún tîkì lati ṣe àseyọrí. Ìgbésẹ̀ pataki yii ṣe iranlọwọ lati mú àdínkù bá tîkì tàbí lati mú àrùn tîkì kùrò patapata nigbamìíràn. Fún apẹẹrẹ, a lè kọ ẹni tí àrùn tîkì ti ọ̀nà ọ̀fun ń ṣe loorekoore ní ẹ̀kọ́ lati rọra máa mí nígbà ti ìṣesí tîkì bá bẹ̀rẹ̀. A lè lo líle ọrùn fún àrùn tîkì tó jẹ mọ́ mími orí. A kọ alaisan lati mọ ìmọ̀lára ìṣesi tîkì ati lati maa le iṣan orí tàbí iṣan ọrùn gẹ́gẹ́ bii èsì tó yàtọ̀.



Àwọn agbegbe kan, àwọn ìpò tàbí àwọn iṣẹṣi kan lè mú kí tîìkì se ni, wọ́n sì lè mú ki tîìkì buru sii. Ibí yii ni ìgbésẹ̀ ìdàsí iṣẹ́ (FI) ti di mímúṣe. Ojúsùn FI ni lati ṣe ìdánimọ̀ àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ojoojúmọ́ tí ó maa ń mú ki àrùn tîìkì buru si kí a sì yí wọn pada lọ́na ti ki yoo mu ki tîìkì ma waye. Fún apẹẹrẹ, ẹnikan ti àrùn tîìkì ń ṣe lemọlemọ nigba tí ó bá ń ṣe iṣẹ́ àmúrelé tàbí ṣaájú sise àfihàn ohun àkọsílẹ̀ ni ibi iṣẹ, a gbọ́dọ̀ kọ irúfẹ́ ẹni bẹẹ lati sàkóṣo àwọn wàhálà yii saaju tàbí lẹyin awọn ìṣẹ̀lẹ̀ yii. Bakanna, a lè gba ẹni tí tîìkì bá ń ṣe lọpọ igba ní ìgbà tí ó bá joko fún ìgbà pipẹ ní àmọ̀ràn lati maa dìdé tàbí sinmi loorekoore ni gbogbo ọjọ naa.

## A ti sọ fún wa nigbagbogbo pé TS jẹ àkùdé iṣan ọpọlọ ati pe tîìkì jẹ ìṣesí ti eniyan kò lagbara lórí rẹ̀. Tí èyí bá jẹ́ òtítọ́, bawo ni CBIT ṣe le ṣiṣẹ́?

Ko si àríyànjiyàn pe tîìkì jẹ àrùn tó jẹ mọ ti ọpọlọ. Sibẹsibẹ, àrùn tîìkì nigbagbogbo tun maa ń ní àjọṣepọ tó gbẹgẹ́ pẹlu agbegbe tí wọn ti ń wáyé. Gbogbo eniyan tí ó ní àrùn TS ti ní ìrírí awọn ìṣẹ̀lẹ̀ kan tí ó mú kí àrun tîìkì wọn buru sii. Bakanna, ọpọlọpọ eniyan tí ó ní àrùn TS mọ̀ pé àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tàbí iṣẹ mìíràn lè ṣe ìrànwọ́ lati mú kí ìwà tîìkì wọn wálẹ̀. CBIT ń gbìyànjú lati ṣe iranlọwọ fún awọn ọmọde ati awọn agbalagba lati mọ ati ṣe ìdánimọ awọn kókó àyíká tí ó le mú kí àrùn tîìkì burú sii. CBIT tún ń kọ́ni bi a ṣe le ṣẹ̀dá awọn agbègbè tí o dúróore diẹ sii, àwọn àgbègbè ti a mọ̀ tẹ́lẹ̀ tí ó sì rọrùn lati ṣàkóso.

## Níwọ̀n ìgbà tí CBIT ń ṣiṣẹ́, ṣe èyí túmọ̀ sí pé awọn eniyan tí ó ní TS ní anfani lati tẹ ìṣesí tîìkì wọn mọ́lẹ̀?

Àwọn eniyan tí wọ́n ní tîìkì le tẹ ìṣesí tîìkì wọ́n mọlẹ̀ lẹ́ẹ̀kọ̀kan ṣugbọn èyí kò túmọ̀ sí pé wọn le ṣàkóso rẹ̀ ní gbogbo ìgbà. Àtẹ̀mọ́lẹ̀ àtinúwá jẹ́ èyí tó nira tí ó sì maa ń lo ni lókun, ó maa ń da ọkan eniyan rú ó sì lè mú kí ìrírà pọ sii. CBIT kii ṣe nkan kan naa pẹlu àtẹ̀mọ́lẹ̀ àtinúwá tîìkì. CBIT ń kọ àwọn eniyan tí ó ní TS ní awọn ọgbọ́n kan pàtó tí wọ́n le lò lati ṣàkóso awọn ìmọ̀lára ìṣesí tîìkì wọn láì lo àtẹ̀mọ́lẹ̀ àtinúwá. Ìlànà ìtọ́jú naa nílo àfọkànsí ati àdáṣe lati kọ́ awọn ìhùwàsí tó ń figagbága pẹlu ìwà tîìkì. CBIT ń ṣe iwúrí fún àdáṣe àwọn idahun tó ń figagbága pẹlu ìwà tîìkì èyí ti dokita gbékalẹ̀. Àwọn idahun tó ń figagbága pẹlu ìwà tîìkì tí a ṣe ní ọ̀nà ìdákẹ́jẹ́ lè mú adinku ba tîìkì, ó sì tún le mú kí alaisan naa ní imọlara iṣakoso díẹ̀ sii.

## Wọ́n ti sọ fún mi pé kí n ma kọbi ara sí tîìkì ọmọ mi nítorí pé ti mo bá jẹ kí ó mọ̀ nipa tîìkì sii, èyí le jẹ kí àrún tîìkì naa burú sii. Sé CBIT kii yoo jẹ ki awọn àrùn tîìkì burú sii?



Tîìkì maa ń burú sii nigba ti a ba kọbi ara sí wọn lápọ̀jù yálà ní ilé, ilé ẹ̀kọ́ tàbí ní ibi isẹ. Ojúsùn CBIT kii se lati mú ki awọn ọmọde ati awọn agbalagba ní àfiyèsí ara-ẹni sii, ṣugbọn lati ní àfiyèsí tîìkì ti wọn ní. Bí awọn eniyan tí wọ́n ni àrùn TS ṣe ń ní àfiyèsí ati òye ohun ti TS jẹ, ara wọn ma ń balẹ̀ wọ́n sì tún maa ń ni èrò ìgbẹ́kẹ̀lé ara-ẹni ati agbara --àwọn èrò ọkan wọnyi ní àjọṣepọ̀ pẹlu àdinku tîìkì, wọn kii mú kí tîìkì pọ̀ sí. Ninu CBIT, èrèdí ìkẹ́kọ̀ọ́ nipa àfiyèsí-ara-ẹni ń seni ní anfani, ó sì maa ń ran alaisan lọ́wọ́ lati ní òye ohun tó lè mú kí àrùn tîìkì wọn lọ tàbí burú sii.

## Mo gbọ pé nigbati awọn eniyan tí ó ní TS bá ń gbiyanju lati dá tîìkì wọn duro, yoo mú kí awọn tîìkì mìíràn buru sii tàbí mú kí tîìkì padà wa lẹyin igba ti ìgbìyànjú lati dáa dúró bá pari. Sé CBIT náà kò ní fa awọn iṣoro wọnyi bí?

CBIT kìí kọ́ ni ní ẹ̀kọ́ àtẹ̀mọ́lẹ̀ àtinúwá, ṣugbọn dípò èyí, ó ń kọ ni ní àwọn ọgbọ́n lati ṣàkóso àwọn ìwà mìíràn tì kò bá àwọn ìṣesí tîìkì mu titi tí ìmọ̀lára ati ìṣesí tîìkì yoo fi dinku tàbí lọ patapata. Híhu àwọn ìwà tí kò bá tîìkì mu kìí ṣe àtẹ̀mọ́lẹ̀ àtinúwá. Ìwádìí ijinlẹ fihàn pé awọn ọgbọn wọnyi ti a lò ninu CBIT kii mú ki tîìkì buru sii tàbí mu ki tîìkì tuntun farahan. Dípò èyì, awọn tîìkì tuntun tàbí mímú kí àwọn tîìkì tó wà lara lọwọlọwọ buru sii jẹ ọkan lara awọn ohun ti a fi ń da TS mọ laifi ti ìtọ́jú se, kìì ṣi ṣe àkùdé CBIT.

## Se CBIT kìí mú kí àwọn ìṣesí tó yatọ sí ti tîìkì di tîìkì tuntun?

Àwọn alaisan tí ó ní TS maa ń ṣe akiyesi pé tîìkì tuntun maa ń farahan lara wọn ati pe awọn tîìkì àtijọ́ maa ń parẹ̀. Èyí ṣábà maa ń wáyé fún TS. Àwọn alaisan maa n kọminú nigbamìíràn pé wíwu awọn ìwá tó lòdì sí ìṣesí tîìkì le dí tîìkì tuntun. Adúpẹ́ pe kò sí ẹ̀rì pé èyí ń wáyé. Àwọn alaisan kii ṣábà jábọ̀ èyí, wọ́n kò sì tii se àyẹ̀wò fun ninu ìwádìí.

## Bawo ni CBIT ṣe munadoko tó fún ẹnikan tí ó ní àrùn TS?

Àwọn ìwádìí tí awọn ilé iṣẹ́ nla, awọn ile isẹ to ní aye pupọ ati awọn ile se ìṣègùn ti orilẹ ede se agbátẹ̀rù fún fi han pe ó lé ní ìdajì awọn tí wọ́n se CBIT maa n ní ìrírí àdinku tîìkì wọn, wọ́n sì maa ń ni agbara lati ṣiṣẹ daradara. Ìmúkúrò àrùn tîìkì ati awọn ààmì àìsàn TS mìíràn patapata máà ń ṣẹlẹ̀ lẹ́ẹ̀kọ̀kan pẹlu CBIT. CBIT kìí ṣe oògùn tí ń wó TS sàn patapata ṣugbọn ó jẹ́ ohun-èlò tí ń ṣé iranlọwọ fún awọn eniyan lati ṣàkóso tîìkì wọn, ó sì maa ń ràn wọ́n lọ́wọ́ lati mú ilọsiwaju didara bá ìgbésì ayé wọn.

## Ṣé CBIT wà fún gbogbo eniyan tí ó ní TS tàbí tîîkì?

Ó ṣe pataki lati ní òye pé kií ṣe gbogbo eniyan ni yoo jẹ anfani CBIT. Kíkọ́ àwọn ọmọde tí wọ́n ni ADHD ti wọ́n kò tọ́jú ní ilana yii lè nira púpọ̀ nitori awọn ìṣòro àìlèpọkànpọ̀, ìṣòrò híhu ìwà láì ronú, ati ìṣòrò àìlè fàyà rán ìṣòrò. Bákannáà, eyikeyi ìṣòro ọpọlọ tàbí ìṣòro àwùjọ tó bá díni lọna lati kópa ninu àwọn ìtọ́jú yẹn lè mú kí CBIT níra sii. A lè lo CBIT láì tọ́jú awọn àkùdé ti wọ́n jọ maa ń wáyé papọ̀, ṣugbọn a gba alaisan nímọ̀ràn lati sètọ́jú eyikeyi awọn àkùdé yẹn pẹlu àyẹ̀wò. Àwọn ìpò tí àgọ́ ara wọn wa tàbí àwọn ààmì aisan lè ṣe ìdíwọ́ fún wọn lati ṣe CBIT.

## Ṣé CBIT rọ̀rún lati ṣe?

CBIT lè dàbí ilànà ìlera tí ó rọ̀rún, ṣugbọn ṣe akiyesi pé ó nílo ìgbìyànjú ati àkókò fún CBIT lati ṣiṣẹ́, bii eyikeyi ọgbọ́n tuntun. CBIT máa ń rọ̀rún bi ọjọ́ ṣe ń nlọ.

## Ṣé ó yẹ kí a lo CBIT gẹgẹbi ìlànà ìtọ́jú àkọ́kọ́, ṣe a lè lòó pẹlu oògùn oyinbo, tàbí sé mo lè dá oògùn mí dúró tó bá jẹ́ pé mò ń lo oògùn?



Ipinnu yii gbọdọ̀ wàyé pẹlu onísẹ́ ètò ilera tí ó yẹ. CBIT ti ń wà ní ibi gbogbo ati pé ó le ṣeé lò bíi ìtọ́jú àkọ́kọ́. A kò gba ni lamọran lati dá oògùn duro tàbí dín oògùn lílò kù ṣaájú bíbẹ̀rẹ̀ CBIT àyàfi tí olútọ́jú alaisan naa ba dábàá rẹ.

## Ní kété tí ó bá ti yéni, ṣé CBIT lé ṣiṣẹ́ ní ìgbésí ayé ẹni titi láí bí?

Ìwádìí kòpẹ́kòpẹ́ kan fi han pè ìdá 87 awọn olùkópa tí wọ́n se daadaa labẹ CBIT ń tẹ̀síwájú lati ṣe daadaa fún oṣù mẹfa lẹyin tí wọ́n ti pari ìtọ́jú naa. Rántí pé CBIT kii ṣe ìwòsàn patapata; ó jẹ́ ìlànà iṣàkóso. Àwọn alaisan yóò kọ́ ẹkọ nípa ìṣàkóso èyí tí wọ́n le lò fún ìyókù ọjọ ayé wọn bí wọ́n ti nílò rẹ.

## Níwọ̀n ìgbà ti CBIT jẹ́ itọju bí a tii ń hùwà, sé ìyẹn túmọ̀ sí kí n fìyà jẹ ọmọ mi nitori ó ní tîîkì, tàbí kii ń tọ́jú rẹ nitori kò ní tîîkì?

Fún ọgbọ̀n (30) ọdún ó lé, awọn akọ́sẹ́kọsẹ́ ti kọ lílo àwọn ilana ìjìyà lati dojúkọ eyikeyi ìṣòro. CBIT kìí lo ìjìyà tàbí gba ni lamọran lati lo ìjìyà lati dojúkọ tîîkì; ìdákejì èyí ní a dúró fún. Nína ọmọ nitori pe ó ní tîîkì tàbí nítorí pe kò lè pa ìṣesí tîîkì rẹ mọ́ra kìí ṣiṣẹ́. Bíbá ọmọ wi, pípariwo mọ́ ọmọ tàbí mímú awọn àǹfàní ọmọ kúro nitori àrùn tîîkì kìí ṣe ìrànwọ́ kankan, ó sì ṣeéṣe kí ó fa ìpòrúurùù ọkan, ó sì ṣeéṣe kí ó mú kí tîîkì naa buru sii. Kìí se ìrànwọ́ kankan lati san ẹ̀san rere fún ọmọ nitori kò ní àrùn tîîkì.



Ọkan ninu awọn ayọ̀ ńlá pe à ń ran ọmọ lọ́wọ́ lati kọ nìpa CBIT ni pínpín ninu ìdùnù wọn nígbà tí wọ́n ba ti mọ àwọn ìlànà ìtọ́jú yi daadaa tí àwọn ààmì tîìkì wọn sì bẹ̀rẹ̀ sí ní dinku. Lati de ìpò yẹn, a fẹ́ kí awọn ọmọde ṣe awọn ìdàhùn tó ń figagbaga pẹlu àwọn ìṣesí tîìkì daadaa, a sì fẹ́ ki awọn òbí san ẹ̀sàn rere fún awọn ọmọ wọn, kí wọ́n sì se àtìlẹyìn fún àwọn ìgbìyànjú wọn (kìí se nitori pe tîìkì wọn dínkù). CBIT lè le lati kọ́, nitorinaa atilẹyin òbí ati awọn akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ ati èsì rere fún ṣíṣe iṣẹ́ lori awọn ètò ìṣàkóso CBIT wọn lè se pàtàkì lati ran ọmọ kan lọwọ ni ìbẹ̀rẹ̀ ìtọ́jú wọn.

## Kíni mo lè se tí ọmọ mi bá kọ̀ lati ṣe àwọn iṣẹ́ CBIT rẹ̀?

Melo ninu wa ló maa ń ṣe awọn ohun tó jẹ anfani fún wa- àwọn nkan bi ṣiṣẹ eré ìdáraya, jíjẹ ounjẹ tó dára, sísun daadaa ní alẹ́ ati bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ? Ṣíṣe ohun titun fún ara-ẹni kìí ṣe ohun tó rọrùn nigbagbogbo. Àwọn ọmọ mìíràn tí wọ́n ni ìpò àìléra TS lè ní ìpènijà kíkọ́ nipa CBIT. Mímọ̀ bí ó ti le koko tó fún wọn, rírán wọn lọ́wọ́ lati ru ẹ̀mí wọn sókè, àti ṣiṣè ìwúrí fùn wọn láti máa gbìyànjú sii ni awọn ipa tí òbí le kó.

Ó tún jẹ́ anfani lati kọ́ awọn ẹlòmìíràn, awọn olùkọ́, awọn oṣiṣẹ ile-iwe ati awọn agbanisiṣẹ ní ẹ̀kọ́ nipa CBIT kí wọn lè ṣe atilẹyin fun awọn akitiyan wọnyi ati iranlọwọ lati ṣẹ̀dá ati ṣètọ́jú agbègbé rere tí ó ṣe pàtàkí fún CBIT lati ṣiṣẹ́ daadaa.

## Níbo ni mo le lọ lati ṣe CBIT?

Akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ onisegun lè kọ́ni ní CBIT, pẹ̀lú àwọn onímọ̀-ìjìnlẹ̀ nìpa bi a tií hùwà, awọn dokita, àwọn nọọsi, awọn oṣiṣẹ àwùjọ, tàbí awọn onísegùn mìíràn. Gẹgẹbi ó se maa ń rí pẹlu eyikeyi itọju, ẹ̀kọ́ ati ọgbọ́n onisegun se pataki fún àbájáde rere. Àwọn ti a gbà lámọ̀ràn lati pèsè ìtọ́jú yii ni àwọn onisegun tí wọ́n ti kọ́ ẹ̀kọ́ nìpa àwọn ìlànà iṣẹ́ ọpọlọ ti ìwà wíwù, tí wọ́n sì ti gba ẹ̀kọ́ lori CBIT. Ó ṣe ni láàánú pé, lọ́wọ́lọ́wọ́ bayii, awọn oṣiṣẹ ile-iwosan diẹ ló ti kọ́ ẹ̀kọ́ nipa CBIT.

Àjọ TAA ń ṣe àgbékalẹ̀ àwọn ètò ẹ̀kọ́ lori CBIT jákèjádò orilẹ̀-ede. Síbẹ̀síbẹ̀, àwọn akọ́ṣẹ́mọ́ṣẹ onisegun tí wọ́n ní ẹ̀kọ́ lori CBIT kò pọ̀. Díẹ̀ ninu awọn akọ́ṣẹ́mọ́ṣẹ ti wọn kò ni ànító ẹ̀kọ́ CBIT yoo gbiyanju lati ṣe itọju naa, ó sì se pataki lati ní òyé pé awọn abajade wọn lè ma dára bíi àwọn abajade tí a gbà lati ọ̀dọ̀ awọn oṣiṣẹ CBIT ti wọ́n ní ìrírí àti ẹ̀kọ́. A gbà ọ niyanju lati farabalẹ̀ yan onisegun rẹ kí o sì beere nípa ẹ̀kọ́ CBIT wọn.



Mímọ ipa tí àìtó awọn dokita tí wọ́n ní ẹ̀kọ́ lori ìwà híhù, tí wọ́n sì lè tọju àìléra Tourette Syndrome ati àwọn Ìṣiṣẹ́gbòdì Tîkì ń kó, Àjọ Tourette ti ṣàgbèkalẹ̀ ilé ẹ̀kọ́ kan tí a mọ̀ si Tourette Syndrome Behavior Therapy Institute (TS-BTI). A gbée kalẹ̀ lati ọwọ́ ágbáríjọpọ̀ àwọn Ẹ́gbẹ Ìmọ̀-ìjìnlẹ̀ nipa Ihuwasi. A piyamọ ètò naa lati mú ki iye àwọn onisegun tí wọ́n ní ẹ̀kọ́ CBIT pọ̀ si. Àwọn ètò naa máa ń wáyé déédé ní àwọn àkókò kan ati ní orisirisi àwọn ojúkò kaakiri orilẹ̀ ede lati ọwọ ẹ̀ka TAA TS-BTI wa. Lẹ́hìn tí ètò naa ati awọn ìpàdé bá ti parí, a o fi orúkọ àwọn olùkópa sí àtòkọ awọn onisegun CBIT èyí ti Àjọ Tourette ń mójútó. Lati kọ́ ẹ̀kọ́ sii tàbí forukọsilẹ̀ fún ètò TS-BTI, jọ̀wọ́ ṣàbẹ̀wò sí tourette.org tàbí pe 888-4TOURET.

## Àkópọ̀

CBIT jẹ́ ìlànà tí ó lágbára tí a ti se àfihàn pé ó lè mú àdínkù ba ìṣesí àrùn tîkì, ó sì tún jẹ́ òye ìgbàlódé lori bí àyíká ṣe lee nipa lori ọpọlọ. Ẹgbẹ́ Tourette ati Àgbáríjọpọ̀ Ẹ́gbẹ Ìmọ̀-ìjìnlẹ̀ nipa Ihuwasi ti fi ara wọn jìn lai maa sọ̀rọ̀ ní ọ̀nà tó yéni lori ohun ti ìwádìí naa jẹ kí a le lo àwọn ìtọ́jú naa lọ́nà tí ó yẹ tí ó sì múnádóko.

## ÀWỌN ÌTỌ́KASÍ


Piacentini, J., Woods, DW, Scahill L., Wilhelm, S., Peterson, AL, Chang, S., Ginsburg, GS, Deckersbach, T., Dziura, J., Levi-Pearl, S., Walkup JT , 2010, IBehavior Therapy for Children with Tourette Disorder: Àyẹ̀wò Oògùn Tí a Ṣàkóso Láìlétò. Jọna àkọsílẹ̀ ti Ẹgbẹ Ìṣègùn ti Amẹrika, 303: 1929-1937.

Woods, D.W., Piacentini, J.C., Chang S.W., Deckersbach, T., Ginsburg, G.S., Peterson, A.L., Scahill, L.D., Walkup, J.T., Wilhelm, S., 2008, Managing Tourette Syndrome. Ìdásí Ìwà fún Awọn ọmọdé ati Agbalagba. Ilé Iṣẹ́ Ìtẹ̀wé ti Ilé-Ẹ̀kọ́ Giga Oxford.

Chang S.W., Piacentini, J. & Walkup, J.T., 2007, Behavioral Treatment of Tourette Syndrome: Ti Àtẹ̀yìnwá, Lọ́wọ́lọ́wọ́, ati Ọjọ́ Iwájú. Clinical Psychology Science and Practice, 14(3):268-273.


## NÍPA ÀGBÁRÍJỌPỌ̀ Ẹ́GBẸ́ ÌMỌ̀-ÌJÌNLẸ̀ NIPA ÌHÙWÀSÍ TI TOURETTE

A dá Ẹ́gbẹ Ìmọ̀-ìjìnlẹ̀ nipa Ihuwasi ti Tourette sílẹ̀ ní ọdún 2001. Àwọn ọmọ ẹgbẹ́ jẹ́ àwọn tí wọ́n ti gba ẹ̀bún owo Àjọ Tourette nigbakan rí, tí wọ́n pejọ lati mu itẹ̀síwájú bá iṣẹ́ yii nìpa ṣìṣe àyẹ̀wò CBIT. Iṣẹ́ pataki àwọn Àgbáríjọpọ̀ Ẹ́gbẹ Ìmọ̀-ìjìnlẹ̀ Ihuwasi ni lati ṣe àgbékalẹ̀, àyẹ̀wò ati ìpínkáàkiri awọn ìwádìí ìtọ́jú àwọn ìhùwàsí tí ó ní ẹ̀rí fún àwọn ọmọde ati àwọn agbalagba tí wọ́n ní àìléra Tourette Syndrome.

## NÍPA AWỌN ÒǸKỌ̀WÉ


Doug Woods, Ph.D., jẹ́ ọmọ ẹgbẹ Àjọ Tourette Association Medical Advisory Board, Igbakeji Profositi fún Àwọn Akẹ́kọ̀ọ́jáde ati àwọn Akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ Elétò Ẹ̀kọ́ ati Ọ̀gá Àgbà ti Ile-iwe Akẹ́kọ̀ọ́jáde ni Ile-ẹkọ giga Marquette.

John Piacentini, Ph.D., ABPP, ni Alaga ti Àgbáríjọpọ̀ Ẹ́gbẹ Ìmọ̀-ìjìnlẹ̀ nipa Ihuwasi ti Tourette ati Ọ̀jọ̀gbọ́n ati Olùdarí Ètò UCLA Child OCD, Anxiety, and Tic Disorders ati TAA Center of Excellence ní UCLA.

John T. Walkup, MD, jẹ́ ọmọ ẹgbẹ́ Tourette Association Board of Directors, Alága Ẹ̀ka Àrùn Ọpọlọ ní Ilé Ìwòsàn Ọmọde ti Ann ati Robert H. Lurie ní Chicago ati Ọ̀jọ̀gbọ́n Ìtọ́jú Àrùn Ọpọlọ ní Ile Ẹkọ Ìṣègùn Yunifasiti Northwestern Feinberg.


A tẹ àtẹ̀jáde yii lati pèsè àlàyé. A gba àwọn idile niyanju lati kọ́kọ́ kàn sí dokita kan nipa gbogbo awọn itọju ati awọn oogun.


Àtìlẹyìn fún awọn ètò ìpolongo ṣeéṣe (ní apákan) Nọmba ìfohùnṣọ̀kan àwọn aláfọwọ́sowọ́pọ̀ IU38DD000727-01 lati Ilé-iṣẹ́ Ìdènà àti Ìsàkóso Àrùn. Àwọn ọ̀rọ̀ tí a ṣàlàyé sinu awọn ìwé àpéjọ tàbí àwọn àtẹ̀jáde ati àwọn ọ̀rọ̀ tí àwọn olùkópa ati awọn olùṣàkóso sọ kò fi gbogbo ara jọ ìwòyé ti Ẹ̀ka Ètò Ìlera ati Iṣẹ́ Ọmọnìyàn, bẹ́ẹ̀ pèlú, pé a dárúkọ àwọn okòwò, iṣẹ́-ajé tàbí ilé-iṣẹ́ kò túmọ̀ sí pe Ìjọba Ilẹ- Amẹrika tí fi òǹtẹ̀ lú irufẹ orúkọ, okòwò, iṣẹ́-ajé tàbí ilé-iṣẹ́ bẹ́ẹ̀.



Àṣẹ Àdáni © 2010

Àtúnse Ẹ̀dà ti Oṣù Keji Ọdun 2019

A gbọ́dọ̀ gba àṣẹ lati ṣe àtúntẹ̀ àtẹ̀jáde yii lọ́nàkọna ní ọwọ Àjọ Tourette ti Ilẹ̀ Amẹrika